# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. II. No. 68. SATURDAY, OCT. 27, 1923. Fourpence.


## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description oj German Goods.*

**"Specisiities: Enamelware, Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruley Plates, Rubber Beeds of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads, etc., etc., etc."**

---

Ọgbẹni **DURO THOMAS**

Onişowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to ṣẹṣẹ de fun u lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Mãse leti ita Faji, l'Eko.

---

## N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

## *J. F. SICK* ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode Ibilai, l'eti *Glover Memorial Hall, (Customs Street,)* EKO.






Awọn Oyinbo Onişowo yi nranṣẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1–4 t' ọlwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranṣẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

Awọn Oyinbo yi nşe orişirişi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranṣẹ *Cement* ati panuikikọle to nipọn, ati ẹja abọmafọ ati orişirişi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA.

ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Ka'awa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun ẹikole fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

---

**B. O. Joseph**

*Commission Agent.*

21 years experience in trade.

**Cotton.**
**Sundries.**
**Hardware.**
**Provisions.**

27, Koseh Street, Lagos.

---

**The British Psychological Institute**

OF BOLTON, ENGLAND,

teaches by Correspondence the following Sciences :—Psychology, Philosophy, Phrenology, etc., etc.

For complete particulars, apply to the Official Representative of the Institute for Nigeria and Gold Coast Colonies

C. GLADSTONE-MACAULAY,
P.O. Box 384,
Lagos.

*Youngmen, for future's sake, be on the alert.*

---

**THE LAGOS HOTEL**

Iced Drinks of every de-scription on sale at the abo[ve] popular Hotel.

Clients' comfort occupies [a] prominent part in the pr-ogramme of the establishme[nt].

Billiards playing formin[g] a centre of attraction.

**TERMS :—Strictly Cash.**

H. H. KIN[G]
*Proprietor.*

Portonovo Market St.,
Lagos.

---

ILE ERO TI EKO.

Ohun mimu Olomi didi to np'ongbẹ en-nbẹ nihin lorişirişi fun tita.

Ko si ọna ti a ko ngba fi tẹ aw[ọn] onibara wa lọrun.

*Billiards* idaraya si wa fun ẹnikẹni lati şere. Owo-lọwọ la fẹ.

H. H. KING,
*Oni-nkan.*

Ita Ọja Ajaşẹ, Eko.

*Editor & Proprietor* :—
ADEOYE DENIGA,
*Office*: 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

———:o:———

A LE F'ẸJỌ IKU SUN LẸSẸ ARUN?

O ṣẹru ba wa nigbati a ri ka ninu Waya *Reuter's Telegrams*) to de sibi ni ogunjọ ṣu yi pe Oyinbo *Lawyer* Ọgbẹni D. H. 'Connor ti o ti nṣiṣẹ nilẹ yi nile Pẹtẹsi gbẹni Adigun Ẹlẹran to sunmọ Sàntáná *Saint Anna*) pẹlu ekeji rẹ Ọgbẹni Wotton okunso niyara rẹ ni Ilu Oyinbo: ẹri ti gbọ pe nwọn jẹ nigbati a *jury* oku ni pe Ọgbẹni na ni ati pada sẹnu iṣẹ on ibi jẹ ohun ibanujẹ fun u, on ko si fẹran fẹfẹ ilẹ yi. A gbọ pe nwọn ni ohun to u Ọgbẹni *Lawyer* na pa ara rẹ niyẹn; kẹdun iku gbigbona bayi a si ba awọn *awyer* ẹgbẹ rẹ toku nibi kẹdun pẹlu.

Ṣugbọn ohun to ṣe wa loju su nipe a o mọ pe ẹnikan le titori pe on ko fẹ ada sẹnu iṣẹ on l'Eko, papa ẹniti o nṣiṣẹ n ara rẹ ti ko si si labẹ ẹnikẹni le torina gba ẹmi ara rẹ lapapa-ndodo bayi; ọran iyan kọ ni pe ko tun pada wa si ko ti ko ba fẹ bẹ. Eyi ha to ohun ti a a fi pokunso si? Awa ko mọ; adura a nipe ki Baba maṣai fori aṣiṣe yi jîn.

BISHOP "AJIṢAFẸ" MBỌ O.

A ki *Bishop* Howells ati Mrs. rẹ kabọ a-ki-lẹ lati ẹnu iṣẹ wọn in' Odo Ọya; *Bishop* na i aya rẹ yio ba ọkọ *Akabo* de ni ọtunla; gbọ pe nwọn gba isinmi diẹ wa sile hin iṣẹ tiantian ti nwọn ti nṣe ni u awọn Ibo lati enu ọdun mẹta wa.

AGUN-T'AṢỌLO, Ẹ K'ATIJỌ!

Bẹ si ni a ki Alufa J. M. Ologundudu bọ lẹnu iṣẹ rẹ ni Sapẹlẹ nibiti o ti wa ni dun diẹ sẹhin; ẹ ku ọfọ ti Iya, ẹ ma si agbe wa fun "Ibi Ayọ" ti a nireti pe ẹ o ṣe fun Iya ninu eyiti ẹ wa'le yi: ki "kọtọ" ọbẹ ma di! ki a si ma gbọ pōpō riro *Champane* niyatọ!! ọna ọfun wa nda gbun silẹ, àgàgá o!!!

AWỌN ARA OWU NWA AWASẸHIN̄ TI IRẸ. IGIDA!!!

Ihin kan ni lati Abẹokuta pe awọn ara Owu sọpe awọn ko fẹ ẹniti o mọwe lati rọpo Ọba Olowu ti o wọ àjà ni oṣu diẹ to kọja ati pe nwọn si ti yan ẹnikan bẹ gẹgẹ; bi eyi ba jẹ ōtọ anu awọn ara Owu na ṣe wa nitoriti o dabi ẹnipe nipa ṣiṣe bayi nwọn ko mọ pe ninu okunkun biri-biri ni nwọn ṣi wa: nigbati awọn erilẹ-ede miran ndu lati tẹ atẹsiwaju ninu imọlẹ iwe mimọ ati oye ati ọgbọn. Igbẹhin lo nbọwa dun oloku ada.

ỌNA'RE O, ẸNYIN AF'ARA FUN'ṢẸ OLUWA.

Awọn Ọgbẹni Dada Adeṣigbin ati Jacob Kanyinde Coker ba Iṣẹ *Church* Ọmọ-Ibilẹ lọ si Ikirun lọsẹ yi; A f'oju sin nyin o.

ANDRE SALAKỌ NLO BẸ'LE WO.

Ọgbẹni yi nda kan lọ wo awọn Ẹbi rẹ ni Agoue ni lọlọyi.

ẸGBẸ IGARA NMI IGBORO TITI.

Lati Ibadan ihin kan ni pe awọ Igárá bẹrẹsi iṣẹ ole wọn; o niye Ile ti a sọ pe nwọn gbe ogun lọ ja loru pẹlu ohun ṣiṣe enia lọṣẹ bi ada ati ọbẹ laika ogun ole ti nwọn nlo. Ṣugbọn a dupẹ pe ọwọ awọn Ọlọpa ibẹ tẹ diẹ ninu wọn.

Shitu Balẹ, Ajẹlẹ Pataki, ẹ dide ki awọn Ogbole wọnyi wọ ki ẹ si ṣe bi àrìrà ki awọn enia nyin le fi ẹdọ le ori ŏrŏrŏ.

### AWỌN WỌNYI HA FẸ BIMỌ BI ?

Gbolohun ọrọ yi la bere lọwọ awọn to ṣe jamba fun awọn ogunlọgọ Bọkinni ti Ọgbẹni Yinusa Animaṣawun ti No. 1, Ita Animaṣawun pe wa si ariya kan to ṣe nigbati o fi nko ọmọ rẹ ọkọnrin ti a ṣeṣẹ bi fun u jade ni Jimọ (*Friday*) ọjọ 19 oṣu yi ; a gbọ pe gigun ni awọn ọmọ-ìna kan gun kẹkẹ ologere (*bicycles*) ti awọn enia gun wa ; awọn to wa ni apejẹ ko si mọ eyi titi o fi di ati lọ sile wọn ni agogo mọkanla oru ; njẹ awọn eleyi ha yọ fun ọlọmọ baun ?

### ỌJỌ KU SI DẸDẸ.

Ọjọ *Wednesday* (Alaruba) to mbọ ni ọjọ ti a fi Ipade akọṣe nipati Igbimọ Aṣofin Ijọba ninu eyiti awọn mẹta ti Ilu yan J. Egerton Shyngle, Eric. O. Moore ati Dr. C. C. Adeniyi-Jones yio bura la'i sin Ọba King niwaju Gomina Clifford Oloye nla G.C.M.G. Kutupu yio fọ ninu "Eko Akete" ti ọsẹ to mbọ nira ti Irohin ọjọ *Wednesday* (Alaruba) na ti a o tẹ sinu Iwe Irohin yi.

### KABỌ, ỌMỌ LAKESI.

A ki Ọgbẹni wa George T. Beckley (*President Native Court*) Abẹokuta, Onidajọ, kabọ fun isinmi oṣu kan to gba ni ọjọ kejidinlogun oṣu yi ; Ọgbẹni yi jẹ aburo Ologbe Joseph O. Beckley ti Agege, ẹniti aworan rẹ han ninu Iwe Irohin ti a npe ni "*West Africa*" ti *September* 22, 1923, nigbati Lieut-Colonel Moorhouse C.M.G., D.S.O. si ọja Agege.

### OKU DIDE JO !

O yani lẹnu o si dun mọ wa lati gbọ pe awọn ara wa ti Ijọ Wesley nilẹyi ṣeṣẹ tun ṣi Ile Iwe tita ti *Mission* won ni Ita Victoria ni'le S. Alfred Coker nibi, ni ọjọ *Tuesday* ọsẹ yi. Apa a ka eyi o !

### O MUSA IṢEGUN !!!

Kosibotiri ni Akanṣe Isin ti Alufa M. S. Cole ṣe ni *Church* Alagogo fun awọn Oniṣegun tiwa lọna t'Oyinbo ni ọjọ 13 oṣu yi. A gbọ pe awọn Oniṣegun mejila lo wa sibi ipade Isin na, awọn Ogunna-gbongbo ninu Iṣegun bi Drs. Oguntola Sapara, Akinwande Savage, John Randle, Kubọlaja Faderin, Orisadipẹ Obasa ati awọn jakan-jakan miran.

---

## "Who's Who."

### AGBE. JAIYEOLA.

Auctioneer & Valuer, aged 42, born at Lagos, the eldest surviving son of the late Thomas W. Dawodu alias Daddy Agbe of Epe. District Lagos educated at St. Peter's and Christ Church Faji Day Schools and at the C. M. S. Grammar School, 1898-99. Served as a junior law clerk under the renowned late Honourable C. Alexander Sapara Williams, C. M. G. and subsequently entered the Lagos Government service as a Telegraph learner in 1901 : is an accomplished Telegraphist. Served in dual capacity as District Clerk, Yoruba interpreter and Deputy Registrar, Benin City, 1905-6. Served in Agbo-Owerrinta Punitive Expedition as operator for the Column when District Commissioner Mr. Crewe-Read was murdered : was mentioned in despatch by the Political Officer Mr. R. A. Roberts, now Senior Resident Onitsha Province and acting: Leiut: Governor. Was promoted to first grade Superintending Clerk Telegraphs in March, 1908. Holder Clerical Service Proficiency Certificate 1912 Resigned in 1914, and proceeded to England, returned home in 1915, December. Was a student at Pitman's College, London. Proceeded to England again in April, 1921, to acquire pratical and theoretical knowledge in auctioneering business : is a registered student of the National University of Dublin, Ireland in the Faculty of Law ; attended series of lectures in Roman Law, Constitutional Law & Legal History and Law of Property in Michealmas Term. 1921. Passed the Entrance Examination for the admission of students to the Irish Bar : is holder of commendable letters from Professor James Munaghan and M. Mc'Neill-Swift M. P. Not having been born with a silver spoon or as a mistletoe to feed from other living trees, has encountered many vicissitudes of life. His first contribution to the local newspaper was "A cry from Macedonia," in 1911. Married in 1911, to Miss Comfort Gbadero, a daughter of the revered townsman and popular auctioneer, Mr. Andrew Wilkinson Thomas. Address 104 Tokunbo Street Lagos

---

The Editor, Eko Akete,

Lagos.

Sir,

I have read with contempt page 5 of the latest issue of the *Nigerian Advocate* bearing the date of October 17, relative to a case between Sadiku Olowonisaiye, a native of Ikorodu, and Sergeant Sanni Bashorun of the Police Force Stationed at Ikorodu. As a true citizen of that place, I consider it a negligence of duty to allow this inaccurate information to remain uncorrected.

Judgment was against he Defendant for £5 damages only and no costs as inserted by the writers in the journal. The writers further pretend to vindicate the interest of the citizens by adding that reports have

eached them to the effect that untried prisoners at Ikorodu re kept to hard labour instead of light work of sweeping the prison compound &c. allowed by the law.

Are the writers truly patriotic? Were they not alive n 1922 when things were actually out of order and Bails not granted in the afternoon? Why the writers do not rever to the cases of so many citizens who have been ruined by means of false Promisary Notes &c. Are they interested? I can assure the Commissoner of Police without any hesitation that the citizens are content with the virtuous movements of the Police now Stationed at Ikorodu and that the story contained in that journal is as virulent as it is worthless.

Thanks Mr. Editor for space allowed

Yours truly,

JOS. M. SHONUBI

## IROHIN ODE ONDO

Lati ọwọ Ijamọ

### IKORE TO BẸ ṢUỌ.

A ṣe isin Ikore ni *Church St. Stephen* Oke Aluko ni ọjọ keje oṣu *October 1923*. Awọn Ojiṣẹ Ọlọrun wọnyi ni o ṣe isin na.

| | | |
|---|---|---|
| Rev. | S. C. Phillips | Alabojuto, |
| „ | T. O. Dedẹkẹ | Alufa Ijọ Oke Aluko, |
| „ | D. A. Oduwusi | Alufa Ijọ Idanre, |
| „ | E. T. B. Adebiyi | Alufa Ijọ Ogbonkowo. |

Isin na dun pupọ ọjọ na ni o si jẹ ọjọ kini ti a kọ ko awọn aga ijoko alarabara si *Church* fun awọn Ijọ lati ma fi joko; o si dun mọ ni pe ko si iyọnu kankan ni ọjọ yi, gbogbo isin na ni awọn enia Ijọ si fi tọwọtọwọ ṣe.

Aṣe yi ṣa mọdun o, ki Ọlọrun da ẹmi wa si di ti amọdun.

### Ẹ F'ẸSỌ ṢE O KO MA BA D'ARIWO!

Ni ọjọ kẹfa oṣu yi ni ija kan ṣẹlẹ ni igboro, larin ọkọnrin kan ati aya rẹ, ọkọ rẹ yi rojọ pe on ba ni ile akọwe kan ati pe ọrẹ rẹ ni akọwe yi nṣe, o si ba obinrin yi ja, obinrin yi si wipe ṣe ni on lọ pe ọkọ on li ẹjọ wipe on fẹ sanwo (*dowry*) fun ọkọ yi, ọkọ yi si wipe ṣe ki iṣe inu yara ni nwọn ti npe ẹjọ, laifa gun lọ titi, obinrin tun lọ si ọdọ akọwe na lati pe ọkọ rẹ li ẹjọ ipa (*warrant to arrest accused*) nwọn si mu ọkọnrin yi, nwọn ti i mọ ile fun ọjọ mẹta, ki a to ri ẹni duro fun u. Ẹjọ ti de ọdọ Adajọ.

### IDANWO TI IJỌBA.

(*Civil Service Entrance Examination*)

Inu wa dun lati sọ pe awọn meji ninu awọn ọmọ Ondo *High School* ṣe dada ninu Idanwo ti Ijọba ni lọlọyi, ki Ọlọrun jẹ ki a ma ri nkan bayi larin ilu wa o.

### "ỌNA IGBORO."

A ko le ṣe alai tun tẹnumọ ti ọna igboro wa. O jẹ ohun abuku pupọ fun ilu wa lati ri pe *Motor* ko le rin ni arin ilu, agbara kaka ni a fi ngun *Bicycle* nibẹ, koto re gegele re ni gbogbo rẹ. A o yọ pupọ bi Ijọba Ibilẹ (*Native Administration*) ba le da eyi ro laipẹ, ki nwọn si bani tun Igboro wa ṣe.

## *Open Letters.*

TO CELEBRITIES, NOTORITIES, ETC., IN DIFFERENT WALKS OF LIFE.

**No. 35.**

To

THE HONOURABLE

DONALD KINGDON,

*Commissioner for the Revision of Laws,*

Attorney-General, Nigeria.

Dutiful Lawgiver,

It is with much satisfaction I learn in *The Nigerian Gazette* of the 18th instant, of the completion by you of the herculean task of compiling and revising *The Nigerian Laws* with which you were charged by the Head of the Executive sometime ago, and which His Excellency The Governor has been graciously pleased to order its use with effect from the 1st *Proximo*.

Pity it is, that I have not been privileged to enjoy your acquaintanceship *vis-a-vis*, since your arrival on our shores, but nevertheless, I share in the high esteem in which you are held by the Bench, the Bar and the public arising from your keen sense of duty coupled with your proverbial kindliness and affability to rich or poor, learned or unlearned, high or low, *black or white* with whom you generally come in contact in this community.

In 1908, Sir Edwin Speed, (then plain Mr. Speed) as Attorney-general of the old Southern Nigeria was entrusted with a mission on all fours with yours, and it is pleasing to note the consummation to which the present work has attained in your hand.

More power to your elbow!

EKO AKETE.

### Change of Address.

Mr. S. T. Ọdẹrinde Ladega begs to inform his friends that he is removing from No. 68 Agodokomeh Street, to No. 5 Okoya Street, (*Idoluwo*) with effect from the 1st of November, 1923, and that all communications intended for him from that date should be directed to the latter address.

## EKO AKETE.

EKO, SATURDAY, OCTOBER 27, 1923.

### LEMỌMU BRAIMAH, JINU, NINU KEU, PẸHINDA.

Aye ko si fun wa tobẹ lọsẹ to kọja lati sọ ọrọ diẹ ṣoki nipa ti iku ẹni nla yi to tẹrigbaṣọ ni ọjọ Jimọh ( *Friday* ) ọsẹ nã; Ẹni yi jẹ ọmọ Lemọmu Ganna ( Hausa ) ẹniti a fi Lemọmu Nala rọ́pò rẹ̀; nigbati Nala ku ni Lemọmu Braimah rọ́pò rẹ̀ ni ọdun 1890—ọdun mẹtalelọgbọn sẹhin—ohun ti a le sọ diẹ nipe ṣãju owo-omi, kosi bi ẹyẹ ati Iyi Lemọmu yi ko ti to larin gbogbo awọn Mušulumi to mbẹ nilẹ yi; nigbati a si ṣi Mọṣalaṣi nla ti Ita Victoria ni ọdun kẹwa ọhun, ( 1913 ) on ni o jẹ pataki ti o "ṣe etutu" si Ile nã lọna ti Isin Larubawa.

Èdèkoyédè owo-omi koṣe owo-omi eyiti awọn Janma na nsọ gẹgẹbi a ti gbọ nigbana pe o fi ẹhin wọn bẹ́lẹ̀ nipa yiyara lọ san owo-omi tirẹ fun awọn Munisipa lalai ba awọn Ianma rẹ sọ mọ; irufẹ iwa eyiti awọn Janma nã ka si Iwa Agbẹhin-b'ẹbọ jẹ, lo mu ki Ọgọ̀rọ̀ awọn enia rẹ ninu Isin Imale ti a nwi yi kẹhin si i.

A fẹ ki a sọ eyi daju; a ko sọ pe awọn Janma Musulumi kọ̀ jalẹ̀ lati san owo-omi, Agbẹdọ, ṣugbọn a gbọ pe o ni ibiti awọn ati Lemọmu nã ti ilẹkun ọrọ nã si ki o to di ogun pe nwọn sọ pe o yi wọn si òbiati nipa lilọ san owo tirẹ lalai sọ fun wọn mọ.

Ikunsinu keji ti awọn Janmã ni si i gẹgẹbi a ti gbọ si nipe nwọn kilọ fun u pe ko si irẹpọ larin Isin Imale ati Isin Ibọriṣa ti yio fi dogun a mba Babalawo kẹgbẹ tabi ṣọrẹ pọ; ọrọ mejeji yi si wa fun iwọn ọdun meje tabi jubẹlọ ki o to wa pari ninu Awẹ to kọja. Ọgbẹni Lemọmu Braimah nã mọ keu jinlẹ gidigidi.

A ka aisan to ṣẽ ni aisan àgbà; ọnakọna si ni onikọ̀-ikẹhin le pe ni lọ s'ile. Awọn Oniṣẹ Ọba t'Oyinbo t'Enia dudu, pẹlupẹlu awọn aimọye Janmã Musulumi ti nwọn lọ sibi oku nã fihan pe A nja bi ka ku kọ. A si sin i si Agbala Mọṣalaṣi Nla ti Ita Victoria ni arọ *Saturday* ọsẹ to kọja ti yio fi di ọjọ Agbende Alukiamọ, ki Ọlọrun fi ọrun kẹ.

A gbọ pe Lemọmu nã to ẹni-adọrin ọdun nigbati o fi ilẹ bora bi aṣọ.

A ko rope o jẹ ohun to tọ si Ọgbẹni Ali Balogun lati fọwọ si Iwe Ikede Oku ti ri ka lode nigbati Lemọmu Braimah dake igbagbọ wa nipe Igbakeji Lemọmu ni eyini ni Naibi rẹ̀ lo tọ si lati fi ọwọ si nã ko si fi sita; kò yẹ ki a fọ́ luru pọ mọ ṣàpà ninu ohunkohun, pãpã ninu Isin Ọlọrun, ibaṣe lọna ti Imale tabi lọna ti Onigbagbọ. Ọrọ kori-kosun ọrẹ kọ̀ niyi tabi ti pe olowo nsọrọ ẹnu rẹ nĩã ina gbajumọ ọ̀tọ̀, olowo ọ̀tọ̀, jagunjagun ọ̀tọ̀, ojiṣẹ-Ọlọrun ọ̀tọ̀, gbogbo rẹ ọ̀tọ̀tọ̀ ni; eto ni lati wà ninu gbogbo nkan—A sọ eyi fun itiju nyin !!!

---

### IKU LEMỌMU BURAIMỌ

*LA ILLAHA ILA ALLAHU.*

[ Nipa ATARI AJANAKU. ]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

ALAGBA,

Ni owurọ ọjọ Jimọ ( Friday ) ọsẹ ti o kọja ni a gbọ wipe LEMỌMU BURAIMỌ di Olõgbe, nwọn si sin oku rẹ si inu iyara kan li ẹhinkule Mọṣalaṣi Jimọ li owurọ ọjọ keji, eyini ni Satide October 20.

O le diẹ ni ọgọfa ọdun ti isin Imale wọ ilẹ yi lati ọna ilu Hausa ati Ilọrin, diẹ ninu awọn Kewu ti o wa ni ilẹ yi nigbana li o si di Imale li ai Kewu ju awọn diẹ ti a kọ ni *Alhamdu Lillahi Rabil alamina, arrahamâni rraheemi* titi de *Wal thuâ leena* lati ma fi ki irun, ati *Subhâna allahi Al Hamdu Lillahi, Alahu Akbar* lati fi fa Teshubã ( Tẹsubã. ) Mọṣalaṣi ko si ni igbana, nitori ẹniko gbọdọ pe irun soke, bikoṣe Ladani ti o npe si inu akeregbe ni ikọkọ ilu. Orukọ ti ara Eko npe isin Imale ni igbana ni "Oriṣa Hausa;" "Oriṣa Eko ko si gbọdọ mọ wipe ara ilu on nbọ Gambari" yi ni igbana.

Nigbati o şe, nkan bęrę si yipada; isin Imale igbilę, nwọn si bęrę si kọ Mọşalaşi kekeke. Awọn ra Olowogbowo, bi Daddy Atęrę, Daddy Thomas (Baba Taba Thomas, Olõgbe;) Ajaramọkewu, Imam agba ti Mọşalaşi "Fourah Bay," Daddy Karimu Thomas, (Baba-baba Ailara Thompson,) Daddy Savage, (Baba Başọrun Olõgbe) ati awọn jakan jakan miran li o tubọ wa fi gbòngbo isin Imale mulę ni ilę yi. Nwọn nawo-nara si nkan sin, awọn kanna si ni aşiwaju ninu ọran ilu pęlu. Ki Ọlọrun fi wọn si afęfę rere.

Awọn ti o ti jẹ Lemọmu li Eko ni:—Baba Lemọmu Nala Olôgbe, Mala Augana, (Baba Lemọmu Buraimọ:) Lemọmu Nala, (Baba Naibi) ti o wa ni isisiyi ati Lemọmu Buraimọ ti o şęşę ku. Salu, ọkan ninu awọn ti o ba Ọba Kosọko lọ si Ẹpę li akoko ọtę, jẹ Lemọmu Ẹpę li ọhun, o si pada wa si Eko lęhinna; on si ni Baba-iya Alhaji Salisu ti Lafiaji.

Lęhin iku Baba Lemọmu Nala ni o wa kan Nala Augana; Ọgbęni yi jẹ ẹrú Ọba Akitoye, Gambari ni. Oninu rere, suru rę si pọ tobę ti a fi npe e ni "Lemọmu Ankuri." O sa ipa pupọ fun idagbasoke isin Imale ni ilę yi, a ko si gbọ orukọ rę pęlu nkan ibaję. O mọ Kewu daradara; şugbọn "alubarika" wipe o jẹ ẹrú Ọba ni ipo Lemọmu fi tę ę lọwọ: nitoripe oye Kewu rę ko pọ to ti Abudulai, (Baba Alufa Abu) ti ita Akanni, bęni ęhin li o si ntọ ti Alufa Mannuel (Aguda) ati ti Baba Abibu Eleto, ti ita Paşi.

Li akoko Mala Augana ni Mọşalaşi ita Akanni di ibiti ilu nkirun Jimọ pataki; ki nşe nitori ohun meji, bikoşe lati bu ọlá ati ọwọ fun Ọba, ẹrú ẹniti Lemọmu ibę nşe. Şiwaju eyi, Mọşalaşi Animaşaun ni a gbọ wipe ilu nkirun Jimọ, ọkan ninu awọn Alufa igbęhin ti o nkirun fun wọn ni ibę ni Abudulai (Tapa,) Baba Sunmọnu Olõgbe.

Lęhin işę ọdun melo kan, Lemọmu Nala ku, nwọn si sin i si itosi Mọşalaşi Jimọ gęgę bi ifę rę ati li ori ilę ti a gbọ wipe o tọrọ lọwọ Gomina Goloba (Glover.) Ẹ sa mọ wipe ibikibi ti o ba wu enia nigbana li o nsin oku si; o si tun jẹ aşa awa enia dudu, ki Oyinbo to de, lati ma sin oku wa si inu ile: şugbọn a gbọ nisisiyi wipe ilę na, li ori ibiti Iboji Lemọmu Nala wa, ọmọ rę Lemọmu Buraimọ ti ta a fun ilu; o si wa li ara ilę Mọşalaşi Jimọ.

Ẹniti o jẹ Lemọmu lęhin iku Nala Augana ni Mọmọdu Nala ti Ebute Awo, ẹniti ọmọ rę jẹ oye Naibi fun Lemọmu Buraimọ gęgę bi Lemọmu Buraimọ papa ti je Naibi fun Lemọmu Nala: li akoko ẹniti ilu toro, ti aiye si roju. Lemọmu Nala şe sā tirę ki o to di ẹni ọrun—a ko sin oku rę si Mọşalaşi Jimọ. Lemọmu Buraimọ Olõgbe li o rọ ipo rę.

Ede-ko-ye'de diẹ wa ki a to we Lawani fun Lemọmu Buraimọ, apakan Janma fę, apakeji ko fę; şugbọn nitori işę rere Baba rę pęlu Kewu ti on papa mọ, Olõgbe Shitta Bey ati Başọrun Savage wa li ęhin rę gbágba, nwọn si şe iranlọwọ nla fun Buraimọ titi o fi jẹ Lemọmu ni iwọn ọdun mejilelọgbọn ti o kọja.

Fun ọpọlọpọ ọdun, li ęhin ti nwọn ti we Lawani fun u ni irępọ ati ifę wa li arin on pęlu awọn Janma (Jamat) rę, şugbọn lati iwọn ọdun męsan sęhin ni ede-ko-ye'de ti de arin wọn, eyi si pọ tobę ti awọn Ijọ rę fi da si meji. Nwọn ko ara wọn de Kótu, awọn ti ko si fę Lemọmu gbidanwo lati yọ ọ, şugbọn gbogbo rę pabo ni; o si dabi ẹni wipe Ijọba wa li ęhin rę. Lemọmu wipe nitori atilęhin ti o nşe fun Ijọba nipasę ọrọ Owo-omi (*Water Rate*) ni awọn Ijọ on fi nbinu, awọn Ijọ rę ni o nşe nkan ti o lodi si isin ni. Li arin ija yi ni ilu fi Abibu Oki jẹ Balogun; li arin ija yi ęwę, ni Oloye Ọbanikoro di ero Mọşalaşi Jimọ. Gbogbo rę di rudurudu bi igbati omi gbigbona da mọ tutu. Boya ija yi iba tete pari bikosi ti awọn onişokoto gbọrọ ti o ti ęsę bọ ọ, ti nwọn si nfo fęrę nibę bi igbati ologini npa eku li oke-aja. Awọn kan ti Anabi ma fi ẹnu wọn jona li a gbọ wipe nwọn nsọ ni igbana wipe "Imale tà ju Koko (*Cocoa*) lọ."

Nigbati akoko Ọlọrun to, O pętu si ija na; awọn ti o ti kọ lati kirun li ęhin Lemọmu Buraimọ ronupiwada, şugbọn ki a ja ki a rę, ko le dabi ọrę apilęşę: papa li ęhin ti awọn Pana-pana ti tu omi le awọn ilu lori ni Mọşalaşi Jimọ nigbati nwọn ngbadura si Ọlọrun, Ọga Ogo, Ọba Mimọ, ani Ọba ti o da ọrun on aiye. *Subhâna nllahi.*

O nlọ si oşu męrin nisisiyi ti Lemọmu Buraimọ dubulę aisan—aisan ti o sọ ọ di ẹni ọrun li owurọ Jimọ ti o kọja; nwọn ko tete tu ọfọ rę fun ilu, bikoşe li ęhin igbati awọn Imale apakeji ti gbọ tan, ti nwọn si ti pari alamọri lati sin i si Mọşalaşi. Lęhinna Alli Balogun fi Iwe Ọfọ (*Obituary Notice*) kede fun gbogbo ilu. Ẹniti o ba fę p'ęgan Ajanaku li o ma sọ wipe on ri nkankan firi—Alli Balogun kuro ni enia pęrę ni ilę yi; li aisi ani-ani, ọkan ninu awọn Opo Mọşalaşi Jimọ ni: sibęsibę, ko tọ si i rara lati kede ọfọ Lemọmu Buraimọ ninu iwe *Obişuari.* Ti a ba fę sin oku Ọgbęni Buraimọ bi Bāle ile, ọmọ rę li o ni lati fi iwe si ode; ti a ba si fę sin i bi Lemomu, Olori awọn Ratibi tabi Igba-keji Lemọmu papa li o ni lati fi iwe si ode.

Ohun ti o tun dabi ẹni wipe o lodi diẹ ni sinsin ti nwọn sin Lemọmu Buraimọ si Mọşalaşi, papa nigbati o jẹ wipe gbogbo awọn Lemọmu ti o ti nku li orişirişi Mọşalaşi ni ilę yi, a ko sin ọkan ninu wọn si Mọşalaşi ri.

Ninu gbogbo "takada" ti mo si ke, ko si eyi ti o yọda fun Imale lati sin oku si Mọşalaşi, ti o ba si wa ki awọn Alufa jọwọ la mi lo ye. A ko sin Anabi Isa si Mọşalaşi, bẹni a ko sin Anabi Buraimọ sibẹ pẹlu. Anabi Mọhọmọdu papa (*Salalahu alaihi wasalamọ*) a ko sin si Mọşalaşi. Shitta Bey, Animaşaun, Mogadi Akiọla, Lemọmu Alalukurani ti ita Paşi ati awọn ẹni nla miran ninu ẹsin Imale ni'lẹyi, ni Abẹokuta, ni Ibadan, ni Ilọrin, ni Zaria, ni Kano, ni Mẹdina ati ni Mẹka (*Mecca*) a ko sin nwọn si Mọşalaşi. Ninu Sura oku jẹ ohun ẹlẹgbin, ti awọn Imale Eko ba si sọ di aşa lati ma sin Lemọmu wọn si Mọşalaşi, njẹ ka to ri ọdun melo kan si, ọpọlọpọ Mọşalaşi ni ilẹ yi yio di itẹ oku igboro kekeke. Iwa ti oku ba hu l'aiye ni yio jihin rẹ l'ọrun bi o tilẹ jẹpe ninu Kaaba ni Mẹka ni a sin oku rẹ si. Nitorina, Kilopo?

Lemọmu Buraimọ şe işẹ rẹ bi Ojişẹ Ọlọrun l'aiye, işẹ rẹ le dara, o si le ma dara loju awa ẹda, şugbọn Ọlọrun nikan li o mọ ẹjọ da!

Ọpọlọpọ kiriyo ni o lọ sibi oku Lemọmu, awọn bi Dokita Randle, Ọbasa, Savage ati Ọgbẹni Henry Carr si lọ pẹlu ninu aşọ oye rẹ. Alhaji Salisu ni a gbọ pe o kirun le oku na lori, şugbọn ko ye wa bi a ti pin itan aja ki o to kan Lemọmu. Nibo ni Alhaji Isa olori awọn oni *Tafseri* ẹniti Alhaji Salisu tẹle wa ni ọjọ na?

Ọrọ ti a o tun tọrọ gafara lati f'ẹnu kan ni oye Naibi ti nwọn njẹ nilẹ yi. Lẹhin Eko, ko tun si ilu Imale miran ti nwọn njẹ irufẹ oye yi nitorina a gba ni imọran pe o to akoko lati pa oye na rẹ kuro li arin wa. Ko tọ suna rara, o si jẹ oye ti o le da rugudu silẹ; nitoripe ẹniti o ba jẹ Naibi, yala o mọ kewu daradara tabi ko mọ ni o, a fẹ lati jẹ oye Lemọmu nigbakigba ti Lemọmu ba ku, bi ilu ba si yan ẹlomiran ti oye kewu rẹ ju ti Naibi lọ, ija a de. Ko si oye Naibi ninu Mudawanọ, Risala ati "takada" miran ti a lana ẹsin ati jẹ Lemọmu si.

Boya ki "Eko Akete" ti ọsẹ yi to jade ni *Saturday October* 27, awọn Ratibi a ti yan Lemọmu miran lati rọpo Buraimọ ologbe nitori ẹnikẹni ti o ba ke *çharhiyat*, (Şẹria) Al-Aathariyyu (Lalari) ati takada miran yio ri nibẹ pe ijọ kẹjọ ti Lemọmu kan ba ku ni a ni lati fi ẹlomiran jẹ; şugbọn ti nwọn ko ba yan ẹnikan titi igbana ki awọn Ratibi tete dorikodo, ki nwọn si yan ẹnikan fun ilu lati fi aşẹ si. Eyi ko kan awọn Kiriyo onişokoto gbọrọ rara, ko si kan Ijọba pẹlu, a si bẹ wọn pupọ ki nwọn maşe da si ọro na—oro ẹsin ni. A si bẹ Ratibi ati Ilu pẹlu pe ẹnikẹni ti nwọn ba yan iba şe Alhaji Isa, Naibi tabi aburo rẹ Alufa Ligadi olohun iyo, tabi ẹlomiran patapata ti Baba rẹ ko jẹ Lemọmu ri, nitori oye Lemọmu ki işe ti idile ẹnikan, ki nwọn jẹ ki oluwarẹ na ti nwọn ba yan tọwọbọ iwe ofin ina esinsin ki njo ni l'ẹmeji, ogun agbọtẹlẹ ko si npa'rọ.

Baba Adini, Sanni Shitta, Mumuni Animaşawun, Alli Balogun, Abibu Oki Balogun, Sanni Adewale, Abudu Ramọnu Aranmọletiẹşọ, Kasumu Gbajabi-amila, Yesufu Agoro, Alufa Salami, Alhaji Sanni Giwa, Kasumu Ayọrinde, Wahabi Shitta, Sumọnu Akangba, Seidu Tella, Asani Ọkunrin-jẹjẹ, Lemọmu Abasi, Bakare King, Belo Pẹpẹ, Sol Shitta, Buari Animanshaun, Brimah Ọbanibasi, gbogbo Ratibi Ilu, ẹnyin Asaru Din, a ke si gbogbo nyin ki ẹ gba imọran wa yẹwo nitori Allah.

Emi ni tiyin nitotọ,

ATARI AJANAKU.

## YI YẸ NI YẸ ẸIYẸLE.

Ni alẹ ogunjọ oşu *October* ni Ilupesi awọn ẹka ẹgbẹ tunluşe (*Ẹnu Ọwa Branch, National Democratic Party*) şe kisa ninu ere wọn fun idunnu ti Alaga wọn J. Egerton Shyngle, Ọlọ Eric O. Moore ati Dr. Ademyi Jones, ti a yan si Igbimọ titun ni lọlọ yi. Ohun pataki ti o ya ni lẹnu ninu ere wọn ni pe ko si amulumala ere ti awọn oyinbo kan ninu rẹ ati pe a ko si gbọ ija tabi ariyanjiyan kankan larin awọn oşere alẹ ijọ na.

"Bi orogun iya ẹni ba mọ jo oyẹ o si tọ k sọ otitọ." Ni alẹ ọjọ yi nigbati mo de Ilupesi pẹkirẹki ijo awọn Gẹlẹdẹ ni mo şe, wo n ẹnikeji! şişe ni emi papa ngun ejika pẹlu wẹ wẹşẹ didun ẹsẹ awọn Gẹlẹdẹ wọnyi; lẹhin ni awọn gbajumọ Obinrin wa ti nwọn joju w bẹrẹ si ere Igbe, yungba ni gbogbo rẹ ndu Mo wa fi ọkan ro pe nigbawo ni ere Onifọ Aka papa yio jade, bi işẹju alakan ni mo gbọ on alẹ-ile ti gbogbo rẹ wa dapọ ti mo ya ẹnu tobẹ itọ fi nkan ni ẹnu mi. Mo wa bere ni ọw ọrẹ mi kan pe bawo ni o ti gbadun ere na şugbọn o dahun pe gbakan şe iran wo ni gbogb ere alẹ na jẹ, Inu mi si dun pupọ lati ri aw Oloye wa Onifila funfun ti nwọn si nrẹrin mu fun işiri ti awọn ẹgbẹ wọnyi fun wọn. Ọgbẹ Lawani Olumẹgbọn ti o jẹ alakoso ẹgbẹ yi n bi arira ati awọn Sẹkitẹri mejeji Ọgbẹni Lawa Ogunro ati Ọgbẹni Belo Fọlajin. Apẹrẹ n ni eyi jẹ fun wa pe nisinsinyi ni a wa şeşẹ nn iyatọ ninu ere ti Oyinbo ati ti ara wa. Ẹny ẹka ẹgbẹ Tunluşe ti Ẹnu Ọwa mo şi fila fi yin. Ki Ọlọrun ki o ran nyin lọwọ si lati şe ohun ribiribi miran nigbati ẹsẹ awọn agbag wa ba ran'lẹ.

AKIRIMANU.

## IGBẸ L' OWO WÀ.

### LAGOS—EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-òwò wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.)
G. B. Ollivant,
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)
MacIver, African
Association, John Holt, Miller Bros.
Cooperative Wholesale Society Ltd.,
Jurgens Colonial Product.
£12—£12 15 fun *ton* kan.

EPO.

£24 10—£25 10 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

COCOA.

£19—£20 fun *ton* kan bakanna.

---

KANO—COMPETITIVE PRICES
Ground Nut—
Skins 1/9 per lb, Hides 4½d per lb

---

## POSI T'O JIRE.

Ẹnikẹni le ri awọn Posi alarabara ti a ti ṣe lọṣọ lati Ilu Ọba wa ra ni ile ọja Kọlade ni 40A Joseph Street, Okepopo, ati ni No. 1, Moloney Bridge St., Anikantamọ. Ọtọtọ ni iye owo wọn, lati £6. 6. titti de 25 guineas. Aṣọ oku (*Shroud*) Yọmini to funfun bi lekeleke si wa nibẹ fun tita pẹlu.

Ẹ lọ ri tabi ki ẹ kọ'we si :—

Ọgbẹni HUDSON COLE,
P.O. Box 477,
Eko.

---

## AIYELẸSỌ ỌLARINDE

Repairer of all kinds of Bicycles, Gramaphones Fitting and Sewing Machines.

*Workshop* :—20, Williams Street Lagos.

*Residence* :—135 Igbosere Road.

**Charges Moderate.**

**Cable Address :—**
" Steinafrik " HAMBURG.

## E. H. STEIN & Co.

**HAMBURG, Neuerwall 16/18, Hildebrandhaus.**
*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos :—
**Mr. Karimu Kotun**
Broad Street, & Portonovo Market Store.

---

ẸGBE OYINBO ONISOWO
E. H. STEIN ARA HAMBURG.
NEUERWALL 16, 18, GERMANY.

Jẹ awọn onişowo ti ilẹ Enia Dudu, nwọn ma nranşẹ Ọja fun ẹnikẹni to ba fẹ, ibaşe Ọja ti ile Gẹsi tabi ti awọn Ilu Oyinbo miran ti o wa lagbegbe *England* ati *Germany*.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ekurọ ti a ba fi ranşẹ si wọn si ilu awọn Oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jọ enia loju.

Ko si ewu kankan ni fi fi Ọja-kọja ranşẹ si wọn lati Eko tabi ilu miran ni *Nigeria*.

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awọn Oyinbo yi şowo lọ ri tabi ki o kọwe si Aşoju wọn nibi Ọgbẹni Karimu Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No. 3, tabi ni ibi-işẹ rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street*) ati ni ibi-ifi Ọja pamọ si (*Porto-novo Market Store*) l'Eko.

Ẹnikẹni le kọwe ni ede Gẹsi, niti *German* tabi niti *French*.

Orukọ adugbo awọn Oyinbo onişowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK, Hamburg.

---

"EKO AKETE" GB'ỌRẸGẸJIGẸ.

A le ri Iwe-irohin yi ra lọdọ :—

(1) Ọgbẹni VIDAL R. COLE, Ajenifuja Store, 109 & 111, Broad Street, Eko.

(2) Ọgbẹni S. A. YEWANDE, 146, Griffith Ebute Meta Street.

(3) Ọgbẹni MOSES O. JONES GOI. Itẹsi, Abẹokuta.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

ROMAN CATHOLIC. (HOLY CROSS)

Masses will be sung by Priests appointed.

Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ,

6.30 7.30 8.30 9.30

7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.

EVENING. 5.45—6.30 p.m.

ANGLICAN

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m.— | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 6.30p.m. | | do. |
| 9 a.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero) | Rev. S. J. Gansallo |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev. J. A. Leigh |
| 6.30 p.m. | | do. |

WESLEYAN

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | do. | „ D. A. Bababunmi |
| 10.30 a.m. | Ereko | „ E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | do. | „ J. A. Angus |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | „ S. A. Pearce |
| 7 p.m. | | „ F. E. Williams |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Bro. D. O. Mould |
| 7 p.m. | | „ C. W. Faulkner-Shaw |

AFRICAN (COMMUNION)

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. G. A. Oke |
| 7 p.m. | do. | „ J. F. Ogunko |
| 9 a.m. | Erelu | Bro. J. H. Lawson |
| 7 p.m. | do. | „ Ignatius Martins |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. J. W. Bara |
| 6.30 p.m. | | „ E. A. Akinọla |
| 9 a.m. | Zion | Bro. O. T. Someful |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. N. J. D. Shomuji |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. L. A. Randle |
| 4.30 p.m. | | „ T. J. A. Green |

FIRST BAPTIST CHURCH

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. S. M. Phillips |
| 6.30 p.m. | | Rev. J. R. Williams |
| 9 a.m. | Ararọmi (Baptist) | Bro. Jeariogbe Tubi |
| 6 p.m. | | „ John Apena |

EBENEZER (BAPTIST)

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Bro. J. F. Oshodi |
| 6.30 p.m. | Rev. E. C. Alabi |

BROTHERHOOD

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | Pastor. A. Adedeji Isọla |
| 7 p.m. | | Prof: Adeoye Deniga |

St. STEPHEN'S (EPETEDO)

9 a.m. & 4 p.m. Rev. A. Adekoya

AHMADIA (ISLAM)

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde

5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajose (Bamgboṣe Street.)

COLONIAL CHURCH (ODAN)

8 a.m.—Holy Communion

6.45 p.m.—Evensong and Sermon, Rev. H. A. Lewis

SALVATION ARMY.

| | |
|---|---|
| 10 a.m. | Capt. A. A. Da Costa |
| 7 p.m. | " " " |

CHURCH OF GOD

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread

7.30 p.m Open Air Service T. W. Walleace & Wm. C. T. Terrel

---


CHANGE OF NAME.

On and from the 1st November, 1923, I generally known as BRAIMA MUSTAPHA (of Sanitary Department, Lagos) now stationed at Ikorodu, desire to be known and addressed as BRAIMA MUSTAPHA DOSUNMU.

B. MUSTAPHA

17th October, 1923.

---

## Change of Name.

Mr. ABDUL-GAPHARR S. FAHM] begs to notify the public that on and from the 1st. day November 1923, he desires to be known and addressed as ABDUL-GAPHARR S. EDIDI.

All papers or documents signed by him prior to that date and bearing the former name remain valid.

*The Ile-Sanmi Chambers,*
*89 Palm Church Street,*
*Lagos, Nigeria.*
*October 22nd. 1923.*

LAGOS STEVEDORING COMPANY.

ALL STEVEDORING WORK

undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.

Estimates given for the handling of goods under any circumstances.

*PRICES ON APPLICATION.*

TO

**S. I. M. Johnson,**

9, Scale Square,

Phone 227 Lagos,

P.O. Box 498.


## AWỌN IWE ỌGBỌNI J. G. KUYẸ

Fun Ile Ẹkọ.

| | | |
|---|---|---|
| A. B. D. Alaworan | ... | 3d. |
| Iwe Alaworan Kini | ... | 7d. |
| Iwe Alaworan Keji | ... | 9d. |

Awọn iwe wọnyi ko ti si lode ni sā kan nitori ogun Germani, ṣugbọn wọn tun de nisisiyi, a si le ri won ra ni Ile Iwe tita ti C.M.S. ninu ilu yi tabi ẹhin odi.

Itan ati owe ti o wa ninu iwe wọnyi dara pupọ, bẹ gẹgẹ ni awokọ inu wọn dara fun ọmọde to, ẹniti o ba dan a wo yio ri pe ọgbọn ẹniti o ti jẹ olukọ awọn ọmọde fun ọdun pupọ li a fi to awọn iwe na lẹsẹsẹ, kiṣe iṣẹ *sare nbaja.*

A le ri awọn iwe wọnyi ra pẹlu lọdọ oniwe ni ẹdin owo, 66, [illegible] Street, Ebute Mẹta.


## *Wool, Wool, Wool.*
## *Silk, Silk, Silk.*

Wulu tabi Siliki lo nfẹ ra ọmọ iya mi? Lọ si Ṣabu Iya Labu, nibẹ ni iwọ yio ri ni orişipe, Wulu ati Siliki lo fi şişẹ şe—Kọbọ ẹru.

(Abulati mbẹ pẹlu bi tẹdi, ọmọ iya Siliki ni.)

18 & 137, Victoria Street.



## JUST THINK OF THAT.



Persons desirous of selling or acquiring Houses or Land in the Colony of Lagos should communicate with

E. SOYEMI ALDER

who for many years has specialised in this class of Property. Sales effected by Public Auction or Private Treaty. Valuation for Mortgage or Probate carefully prepared. Loans arranged Commissions reasonable.

☞ Please note address:—E. Soyemi Alder, Auctioneer, Valuer, etc., Owode (opposite the Law Courts) Tinubu Square, Lagos.



The S.S. "Epe" Sailing on Monday from Ebute-ero wharf to:—

| | | |
|---|---|---|
| SAPELE | — | £2. 5. 0 |
| EPE — | — | £0. 6. 0 |
| EJINRIN | — | £0. 5. 0 |
| KOKO — | — | £2. 2. 0 |
| GBEKAEBO | — | £0. 17 6 |

calling at intermidiate stations fare to and fro can be obtained from the Clerk-in-charge at Ebute-Ero Office.

African and Eastern Corporation Limited, Ebute-Ero.



Ọkọ a ya-ra bi aşa ti a npe ni "Ẹpẹ" yio şi ni Ọjọ-jọ *Monday* lati lọ si:—

Sapẹlẹ, Ẹpẹ, Ejinrin, Koko, ati Gbekabọ. Owo wiwọ kọ ni wọnyi:—£2. 5. 0, 6/-, 5/-, £2. 2. 0, 17/6. yio si ma ya ni egure-egure. Ọpọku oyẹku ni owo ọkọ yi, o si rọju ju ti awọn oyinbo olọkọ miran lọ.

Bere ni ọdọ Akọwe awọn Oyinbo yi

African & Eastern Corporation Limited.

Ebute - Ero.



## ẸNIKEJI,

Aşọ Oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku Ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3 St. John Street, l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

## AWORAN ALARABARA.

A ni Aworan oniruru fun tita lati fi şe ile l'oşo. A ni ti titę oku Jesu, ti igbati a da a lębi iku, ti onję alę ikęhin, t'owo lowo, a ni ti Adam ati Efa, ti işędalę aiye, ti Nebuchadenezar nigbati o wa ninu ola ati ijǫba rę ati nigbati o di ęranko, ti obinrin ti o fi ǫwǫ mu ejo, ti Ǫba Tatambulu.

Awǫn Aworan wǫnyi mbę bi aba, nwǫn si pǫ tase. Bi o ba fę ko pupǫ, a le din ǫ ni owo dię ki o ba le ri tirę ję. Iye owo wǫn 3d, 4d, 5d, 6d, fun ǫkǫkan. 2/6d, 3/-, 4/-, 5/6d fun mejila tabi *dozen*.

A ni Ewe-taba fun kika ta, Ǫşę-olowǫ agaga, Iyǫ-iyǫ mbę lowǫ bi wǫbu, bi o ba fę tǫn a le ta a fun ǫ. Işana alapoti fun tita ko si bi a ti nşe wǫn, orişirişi ǫja lo wa lowǫ wa, iwǫ ko le ba wa şowo ko ma ri tirę ję, nitori owo pǫku ni a nta wǫn, owo ǫja wa rǫju tekǫja ala. Bi o ba wa si ile Ǫja wa, kami-kami ni gbogbo wǫn, bi o ba fę ja irǫ wa, rin wa sibę.

Ibikibi ti o ba ngbe ni *Nigeria* tabi ęhin okun kǫwe şowǫ yala ni ede Gęsi tabi ti Yoruba si :—

E. O. AMBĘ & BROS.,
38, Moloney Bridge Street, Lagos,
( *Lęgbę awǫn Onişowo A. J. Tangalakis* )
Ishimagbo.

---

## FOR SALE.

One Second Handed Triumph Motor Cycle in good working order.

Kick Start, $3\frac{1}{2}$ H.P. with best magneto ( Bosch ) complete with front and rear lamps. Available for inspection.

*PRICE : MODERATE.*

Apply to the Editor.

---

## NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete".

## AKIYESI.

Ti ę ba fę lǫ si ǫdǫ awǫn ti o polowo ǫja sinu Iwe-irohin yi, ę jare ę so pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ę ti ri ipolowo ǫja na ka.


## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trade*

has on hand Woollens in endless var at 50, Dosunmu Street, Lagos,

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

---

OGUN YANMUYANMU ATI EŞINŞIN.

( *Fly Catcher.* )

Eşe ti o fi nję ki Yanmuyanmu Eşinşin ko arun ba ǫ, nigbati ogun re ni arǫwǫto re. Ęgbęrun pere ni Ędęgbarun fun mejila ( 2/3d a dozen

A si ni ipari olorun amu irun daradara, o si ma nję ki irun sunm nję ki o ma kǫmǫna bi jigin, ari mal pada ęhin. ( *Hair preparations.* )

Kǫwe tabi bere l'ǫdǫ

DIPO TUNDE & Co,
P.O. Box 335,
30, Victoria R
Lagos, Nig

---

A CHANCE FOR THE FI

IN THESE *HARD TIMES*!!!

Wanted, a good Salesman capa managing

***A Goods Shop***

*Salary Liberal.*

Only those with substantial Security apply to the EDITO this paper

---

*Ibi ni ęnyin ro si mi—Şugb a mǫ si*

ǪKANLAWǪN BALOGU BROTHE

Dealers in best quality of Produce viz:— Kernels, Palm Oil, Skins of any kind etc., etc

*Head Office* :—16, BANKOLE STREET, La

*Branches at* :—Lagos, Agege, Agbado, Ifo, Wasinmi, Owowo, Ilara, Lafe Ibadan, Ileigbo, Iwo, Ikirun Oshogbo.

*A trial order will be thankfully solicited.*


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.